# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No 765 SATURDAY AUGUST 8 1964 (2D)


## Egbẹ Ọdọ Afẹnifẹre Kọ Iwe Ibo Si Abubakar

IBADAN:- Awọn ọmọ ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre ni Ibadan ati agbegbe rẹ kọ iwe ẹbẹ lati tete le dibo si ile igbimọ Ijọba ti aṣofin ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Ọlọla Abubakar lati le lo ipo rẹ rere si ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ki ibo titun le tete waiye.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre na tun se alaye sinu iwe ti nwọn kọ si Alakoso apapo Ijọba ilẹ Naijiria ni pe lai jẹ pe eto ibo titun tete waiye ni ipinlẹ na pe ko le si Ifọkanbalẹ ni ipinlẹ na ati pe eto alafia

Ijoba rere ko le waiye ni Ipinlẹ Iwọ Orun rara, Awọn Ọmọ ẹgbẹ na tun sọ pe ọpọlọpọ ẹmi lo ti ṣegbe ati awọn ohun ini awọn enia ni ipinlẹ na lo si ti pẹlu, awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre na tun sọ pe ti nwọn ba tete ṣe eto gẹgẹbi ibo yio ṣe le tete waiye ni ipinlẹ Iwọ Orun lo le fi opin si nkan to nṣẹlẹ ni ipinlẹ na

Ni ipari ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ na si ọlọla, Alhaji Abubakar ni o jẹ ohun ti o fi oju rẹ ri lati igba ti o de lati ipade ti o lọ ṣe ni Cairo pe ko si ofin rere ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

# BENSON FESI ỌRỌ WAZIRI LORI IDA ṢILẸ AWOLỌWỌ

EKO:- Alakoso eto irohin fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Oloye T. O S Benson sọ ninu esi ọrọ rẹ eyiti Alhaji Waziri Ibrahim, Alakoso eto aje ati okan ninu Olori ẹgbẹ Olori N P C sọ ni ilu Kalaba fun awọn ọmọ ẹgbẹ olori N P C pe Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti o wa ni ọgba ẹwọn Kalaba nibi ti yio ti lo ọdun mẹwa lọgba ẹwọn yio lo ọdun mẹwa lọgba ẹwọn gbako ati pe nwọn ko ni da Oloye Awolọwọ silẹ rara.

Alhaji Ibrahim Waziri sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pe



Oloye T. O. S. BENSON

ile ẹjọ giga julọ ti na oloye Awolọwọ l'ẹbi ati pe o ni ati lo ọdun mẹwa na l'ọgba ẹwọn. Alhaji Ibrahim sọ pe ẹgbẹ on Olori (N. P. C) ko ni ba ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣẹ pọ lailai lati jọ ṣe akoso Ijọba.

Alhaji Ibrahim Waziri tun sọ pe fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pe to ba di asoko ipolowo ibo si ile igbimọ aṣofin ti apapo Ijọba pe pẹlu iyalẹnu niyio jẹ fun awọn enia ni ipinlẹ Ila orun nigbati awọn yio wa polowo ibo

Ninu esi ti Oloye T. O. S, Benson sọ ninu ọrọ rẹ pe gbogbo ọrọ ti Alhaji Waziri Ibrahim lori ọrọ ti o sọ nipa ida silẹ Oloye Awolọwọ Oloye Benson sọ ninu ọrọ rẹ pe gbogbo ọrọ ti Alhaji Waziri sọ ko mu ọgbọn lọwọ rara ati pe gbogbo ọrọ ti Alha Ibrahim sọ pe ko si ninu awọn ẹgbẹ ose u to le bẹ sọrọ ati pe Alhaji Ibrahim Waziri ko si ro ehin ọla rara lori ọrọ rẹ pe ki nwọn ma fi Oloye Awolọwọ silẹ,



Oloye AWOLỌWỌ

Oloye T. O, S, Benson tun sọ ninu ọrọ rẹ pe ogba ẹwọn ti Oloye Awolowọ wa bayi ki iṣẹ ohun itẹlọruu ati pe ki ẹnikan ma ṣe ro pe ọgba Ẹwọn ti Oloye Awolọwọ wa bayi pe Adanu lo jẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre nikan Oloye Benson sọ pe adanu pe Oloye Awọlọwọ wa lọgba ẹwọn jẹ ti gbogbo orilẹ ede Naijiria ati fun gbogbo awọn ọmọ Yoruba ni pataki.

### ỌRẸ ATATA

Oloye Benşon si tun sọ pe awọn to ba ni ẹkọ Ijinlẹ yio gbagbọ pe ọrọ nipa eto Oṣelu ki iṣe ohun ti enia kan ile di mọra pupọ ju eto pe nkan ti o si ti han gbangba si oju gbogbo enia pe ko si ẹni to le sọ pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ le papọ mọ lailai Oloye Benson si tun ṣe alaye lori ti ilu Congo pe yio fun jẹ apẹrẹ.

Oloye Benson tun ṣe ape juwe gẹgẹbi Ọgbẹni Tshombe ati Lumumba ti wa gẹgẹbi nwọn ti jijọ wa gẹgẹbi ọta tẹlẹ ṣugbọn nisisiyi awọn mejeji na si ti jijọ wa gegẹbi ọrẹ atata bayi.

Oloye Benson sọ pe gẹgẹbi ija ti ṣe wa larin Oloye Awolọwọ ati Oloye Akinọla bayi Oloye Benson sọ.

pe awọn mejeji na si le tun wa gẹgẹbi ọrẹ atata lẹhin ọla.

Oloye Benson sọ pe enia kan ko le ma ni ọrọ lai ..a a ro siwaju Oloye Benson sọ pe ọpọlọpọ awọn enia lo jẹ pe nwọn si lu ofin to jẹ oburu pupọ ti nwọn si ngba ẹbẹ wọn ati ọpọlọpọ awọn enia na lo si nṣe ohun to dara ni ilẹ Naijiria lode oni·

Oloye Benson sọ gbogbo ọrọ ti Alhaji Waziri l ri pe ki nwọn ma da Oloye Awolọwọ silẹ ko si gbọdọ waiye rara. Oloye Benson sọpe ti nwọn ba ngba ẹbẹ iru awọn enia bi Christine Keleer pe ireti wa fun oloye Awolọwọ pe yio jade kuro lọgba ẹwọn.

Ninu ipari ọrọ Oloye Benson, o ro gbogbo awọn enia ilẹ Naijiria ati papa fun awọn Olufẹ Oloye Awolọwọ pe ki olukuluku lo si lati ma kegbe Oloye Awolọwọ kakiri ati pe Alakoso Ijọba apapo ilẹ Naijiria Ọlọla Abubakar ti sọ ninu ọrọ rẹ laseko ti ile ẹjọ giga julọ kọ ẹbẹ Oloye Awolọwọ silẹ ati pe ki nwọn ye kegbe Oloye Awolọwọ

## Rogbodiyan Bẹsilẹ Lori Ẹniti Yio J'ọba Ilu Eko

EKO:- Ni ọjọ Ẹti ti ise ọjọ kẹje oşu yi ni irohin tun de ọwọ wa pe rogbodiyan kan tun bẹ silẹ lori awọn ọmọ Ọba idilẹ ẹniti yio jẹ Ọba. rogbodiyan na ṣẹlẹ nigba i nwọn gbọ irohin po nwọn ti yan Oloye Aminu Kosọkọ gẹgẹbi ẹniti yie wa ni ipo Ologbe Adeie to waja ninu to kọja

Oloye Aminu Kosọkọ jẹ ọkan ninu awọn Oloye marun ti edeaiyede bẹ silẹ larin wọn ati Ologbe Ọba Adeniji Adele eyi to mu ki Ijọba Apapo fi da awọn Ọba na duro lori Oye.

Ni ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni awọn idile meji kan to tọna lati jọba Akinṣemoyin ati Addo-Sọkun si ṣe ipade kan lati bere idi rẹ ti idile Eshilokun fi le mu Oloye Amiuu Kosọkọ gẹgẹbi ẹniti Ọba ilu Eko tọ si.

### IPADE

yi. Oloye Kosọkọ fi ye oni we irohin wa pe o jẹ ohun iyalẹnu fun o l ati gbọ pe on njadu ipo Ọba ilu Eko eyiti Ologbe Ọba Adele fi silẹ l'oṣu to kọja.

W O OJU EWE KẸFA

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Kẹjọ)

LATI ỌWỌ :—

**J. O. Shoyinka**

AWỌN ỌRẸ AYUNỌRUNBỌ LẸNU BODE AWỌN ẸẸKỌ ỌLỌRUN.

Ẹyiti eşu iba fi ọwọ kan ilẹkun atari ni cfi nşe ilẹkun gbẹngbẹngbẹn nwọn ko gbin pẹnkẹn nwọn nwoye şaa lọgan ni oni bode şi ilẹkun awọn ati esu wole,

Eşu fa wọn le onibode lọwọ lati ma tọju wọn titi ọjọ keje ti on nfi pada wa ko wọn, wọn nje, nwọn nmu, nwọn si nfi igbadun şayọ awọn papa ti gbagbe iya ti cti jẹ wọn sẹhin.

Awọn ọrẹ Ayunọrunbọ wọ lu awọn Ẹẹkọ Ọlọrun ariwota gee nigbati awọn Ẹ ẹ kọ Ọlọrun foju kan wọn ẹ kabọ, ẹkabọ gba ilu kan kori kunto kosi ni dun to ti nko ba sapejuwe diẹ niun nyin bi ilu yi ti ri.

Ilu yi kere pupọ odo kekere kan li o pala ibẹ ati ọrun apadi ko si igi tabi koriko an nibẹ ile wọn ndan gbinrin bi awojiji kosi orun kosi ọsan tabi oru gbogbo iẹri bakanna ohun ti o buruju ni ilu yi ni pe nwọn ki sin Ọlọrun afi esu nwọn ya ere kan si ojude olori wọn oga to ẹsẹ mejila eyiyı ni nwọn nbọ. Ki nma purọ awọn obinrin ti o wa nibẹ le ni ẹgbẹgbẹrin ọna ẹgbẹrun ewa wọn ko şe fẹnu sọ. ko si ẹburewa nibẹ rara nigbati awọn ọrẹ Ayọrunbọ foju kan wọn, inu ọpọlọpọ wọn daru nwọn bẹrẹsi tẹ ifẹkufọ ara wọn lọrun. Ọkan wọn balẹ tobẹẹ ti nfi jẹ pe nwọn kofẹ fi ilu na silẹ mọ.

Nigbati odi ọjọ keji oni bode mi nwọn lọsi ọdọ olori ilu Ẹẹkọ Ọlọrun, nigbati o foju kan wọn. oni ẹyin ero nibo ni e nlọ? nwọn ko nwọn ro fun. bi nwọn tise ba Ayunọrunbọ wasi orun ati bi esu tise fa wọn mora tio ya wọn kuro lẹhin ogiriwo. Olori ilu e ẹkọ Ọlọrun ki wọn lẹ keji osi paşẹ pe ki nwọn lọ fi wọn wọ sl afin on Oreko olori ilu Ẹẹkọ Ọlọrun na a ma jẹ ẹni ibi adọrin ọdun li o se li ọrun apadi ki o sa mọ esu lọwọ eyi ni osi di atipo ni ilu ẹ ekọ Ọlọrun.

Irolẹ ọjọ na ko se fẹnu şọ nwọn jẹ nwọn yọ nwọn tun fi oba lee itumọ eyi nipe nwọn mu ọti ata a orun de Ẹni-ibi si tun na lase pe ki ọkan ninu awọn ọmọ ọdọ rẹ lọ tẹni fun wọn o si fi eti ko leti pe ki o da werepe sori ẹni wọn osi da si kitakita di wọ lori eni nwọn fi igbogbo ara kọ werepe odi bo lọ yago fun mi nwọn nki gbe gbee nwọn họra titi ara wọn fi bo yanmọkan Ẹni bii ko jade nigbati ori e o ti rẹ wọn tan orọra jade,

Ẹnyin ọrẹ şe ko si ọkan o nwọn ni ẹwa wa, obu sẹrin o ni ki i bo yin lara bayi wọn ni ara hiho aho de inu egungun ni, oni, şe ẹo le lo ogun ti ngo fun yin yi? nwọn ni awọn yio loo oda ata gigun po mọ atike o funfun lau nwọn şe bi ati ke ni

Ẹni ibi gbe le wọn lọwọ ani ẹ gba ẹ le gbogbo ọgbẹ ara nyin ni yio san kiakia ẹ o si ma jo pẹlu ayọ Ẹni ibi ki ilu mọlẹ oulu bayi pe ohun ti oju wn loju ri ẹma jijo iya kawo panla igi şai şai şai awọn ọrẹ Aynnọrunbọ bẹrẹsi fo soke bi ẹnipe wọn njo şugbọn ata li o nta wọn lara Awọn Ẹ e kọ Ọlọrun ro ba yi wọn kan nwọn nfi wọn şe fẹ ara bẹrẹ si ta wọn gboo Gbogbo ara wọn si hun jọ bi ti Agilinti wni Ibi na wọn ni ina kuna ni lba ki pişan mọlẹ ofin Ẹọn tinu tẹhin ona wọn to wẹ gẹẹ ti ofi jẹ pe nse ni wọn nmi hẹlẹ hẹlẹ tin wọn si npọ ka iku ẹda to ba ribi nwọn ti şe na awọn ọrẹ Ayọrunbọ yio kanu ikunlẹ abiya mọ

Nigbati ẹni ibi tẹ ifẹ ara rẹ lọrun tan oni ẹniti ẹnyin ti ẹ wayi idan yi ẹtẹti lelẹ ki ẹgbọ mi ni agbọye iya ti mo fi jẹ nyin kekere ni ti ọrun Apadi la gongo obu aya o gontiọ pẹlu nigbati mo wa ni ile Aiye awọn araiye ama sẹfẹ pe njẹ ki ẹma fi ina kọ ara wa nitori Ọrun apadi apara la feyi da ina Ọrun apadi ko se fẹnu şọ Ngo fa nyin le Ọba Ọrun Apadi lọwọ yio si mu nyin lọsi Ọrun apadi ẹ ba Ogun lọgọ e n i a nibẹ, nwọn nşe ẹsin, şọra ninu ina hẹ hẹ hẹ irara ibẹ ko şe fẹnu sọ, nibẹ ni e o ti yin ohun ti ẹ o şe ni ile aiye, yio fi ibiti eşu ti nda ẹda han yin ilu ẹjọ ati ọna aiye.

Ẹ bọsi ehin kule ki ẹ wẹ, nitori Eşu fẹrẹ de, nwọn wẹ nwọn mọ sọn.

O fun wọn ni onjẹ sugbọn ẹnu wọn ko ran, nigbati nwọn nranti iya ati o wa niwaju, ki a mọ sa, Ẹnibi ti pin fun wọn tan, ni Eşu wọle ọkunrin kukuru, ko ga ju igo lọ, o rẹrin musẹn, o ni ẹnyin ọrẹ, bawo ni ẹ ti gbadun ilu wa yi si? Ọ r ọ pa esi jẹ, o ni ẹ tẹle mi nwọn si tẹle pẹlu t u l a s i nwọn ko iti rinju idaji busọ lọ, ti ilẹ fi bẹ ẹsi gbona mọ wọn lẹsẹ wọn a pa mora, şugbọn ọkan ninu wọn baraje. o ni ye! ye paripa ilẹ lo njo ni lẹsẹ bayi Eşu rẹrin musẹn, o ni pa ẹru rẹ mọ a ki sọ pe gbona, ilẹ tutu ni a nwi.

Irin ti wọn nrin lasiko yi wa mu ọrin wa bi ẹni ntiro, bi ẹni iraga ni wọn nrin Eşu bẹrẹsi rẹrin ko sọrọ şugbọn ohun ti o ya wọn lẹnu nipe bi Eşu ti nlọ niwaju wọn ti nwọn si ntẹle ẹsẹ rẹ ko kanlẹ rara nşe lọ nra lọ dẹ ẹ bi ẹiyẹ aşa ki wọn to de ẹnu ọna Ọrun Apadi ẹsẹ wọn ti se o ri tolo ni kukuru nwọn de ẹnu bode Ọrun Apadi Akọle ti wọn kọ si ẹnu ọna ọrun Apadi ni yi

ỌRUN APADI ILU IYA ILU AWỌN ẸNI ẸGBẸ

Bi nwọn ti nka ni nwọn ki ọwọ ọna si njo lala nwọn ki gbe irura pe Oro! Oro Oro!!

he! he !! he-e-e!! ọkan wọn tubọ pami bamubamu esu ni ẹba ara nyin sọ ohun tiẹ o ba sọ nisisiyi nitori ajọsọ tabi apero ko si ni ọrun apadi mọ.

ỌKAN NINU WỌN BẸRẸ SI SỌRỌ

Ọrọ na wa doju rẹ gan ọsẹ bi ọkunrin ẹ fara di iya ki şe aimọse wa lo gbe wa de hin asise ko kan ọgbọn ohunkohun to ba de si ẹda ko gba kadara ti o ba se pe ako fi inu meji tẹle Ayunọrunbọ wa ao jiya nitotọ, sugbọn a o bori nigbẹhin gẹgẹbi ọba ọrun apadi tise sọ pe ako ni mọ ara wa mọ ibikibi ti olukuluku nyin ba wa ẹse bi ọkunrin ko si ohun ti o wa ti ki i lopin lọjọ kan a o bo ninu iya yi a o si pada sile aiye ni alafia arikọgbọn li eyisi jẹ fun wa

IYOKU DI ỌLA


Bi O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi Iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
KỌWE SI ILE—IŞẸ—ẸRỌ ITẸ IWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OHO PỌỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹkan şoşo ko si ri iyatọ

# ỌTELEMUYE EKO

Ọtẹlẹmuyẹn nki nyin o, ẹ ku Ọginitin yi o, Oluwa Alanu ko ni jẹ ki ẹ ba Otutu yi lọ o Aṣẹ

LỌWỌ IKU OJIJI OLUWA RERE GBA WA O

Eyi ni lati tun fi si etigbọ awọn Ọlọpa, papajulọ balẹ papa lanto lati moju tọrọyi, ki Iku ojiji ba le dawọ duro ni Abule yi.

Awọn ti o ntaja ni Ga rẹji papajuto ko bikita fun ẹmi wọn, Igbakugba ni moto ma nṣẹ wọn lẹsẹ, Ohun ti o si fa ni wipe, Oju ti i ni wọn ma nkiri Agbado ati Ireke, nṣe ni wọn si ma nsure le moto bi ijaa, Emi Ọtẹlẹmuyẹn keke ke wọu ko gbọ. wọn ko gba Bale papalanto ọrọ to wa dọwọ nyin o.

Igbakugba ni ngo ma sọ awọn olorikunkun yi ti wọn ba gbo, nwo tun mu ọrọ wọn lọ siwaju ijọba Iwọ Orun ati ọba Ọlọpa Apapọ Na jiria fun imojuto

ẸNYIN ENIA, Ẹ BẸRU ẸMI NYIN

Emi Ọtẹlẹmuyẹn ti nṣe akiyesi pe awọn ara Eko ko bẹru Iku ojiji. Ohun ti omu mi sọ bẹ ni pe wọu ki ya fun kẹkẹ, moto, papa wọn ma nba duna ni,

Ọpọlọpọ awọn ara Eko ama fi ẹnit o ba nsa fun moto tabi kẹkọ ṣe yẹyẹ pe afa afadahori ni wọn; ede Omugọ patapata gba ni eyi Ọlaju kan ho si ninu peki enia ma ba Iku dọgbọn.

Ẹniti kẹkẹ ba kọlu ti ko ba ọa moso di eni Lakuregbe tabi Arungun., Bi o ba si se li moto ni le sọ Oluwa rẹ di Arọ tabi tabi ẹniti ko ba gbadun lailai.

Nitori idi eyi mo bẹ ẹyin ara Eko kiẹ ye fi oju di mọto tabi kẹkẹ mọ ki a ba jẹbi iku lati aiye lọ dọrun Ẹniti o ba ti o i lati gbọ ki o gbọ Ọtẹlẹmuyẹn wi tirẹ o.

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 21-Feb 18) Titi ọjọ meje loni iwọ yio ridi ohun ti o nda ọ lamu bi o ba si ri ounimọran, oda ra ki ọ gba maṣe ba ẹnikeni jiyan maṣe ṣiṣẹ Overtim anfani yio si wa ninu ohun ti o ba tẹs waju

PICES (Feb 19-Mar 20) Sọ ara rẹ, maṣe jẹbi Ọgbọn ati ero rẹ lọ ki o si ma ronu wo ki o to ṣe kan, maṣe ṣere gele loni ki o si le tete dubulẹ nigbati ilẹ ba ṣu

ARIES (Mar 21- April 20) Nisisiyi ti o je wipe fun iwọn ọjọ meje loni Ọlọrun koni gba ọjọ ọsẹ lọwọ rẹ ki o si gbe satunde le ọ lọwọ mura ki o ṣe ọkunrin, tete ma dubulẹ ni alale, ki o le tete ma sun.

TAURUS (April 21-May 20) Lọ gba afẹfẹ nigbati ẹfufu gbe wa ma si ṣe sọ ohun kan laiuidi, Ronu jinlẹ ki o to ba enia jiyan

GEMIGI (May 21-June 22) Nitori alamọri ṣe tio nlọ dara dara yi, o tọ ki o daro bi iwọ yio ti fi opin si erokero gbẹkele ara re.

CANCER (June 22-July 22) Gbogbo irawọ Ọrun ni yio ti ọ lẹhin loni, iwọ yio si ere nla ka loni ṣugbọn ṣọra ipa ala ti ko ni ṣe lati marọ.

LEO(July23-Aug22)Maṣe lero ninu okan wipe ohun kan ti o ṣo li aṣe yori ni tori na o si ti ṣe ohun nlẹ ninu ara rẹ nfẹ alafia mura ki o jẹbi ya ti o nlẹ nilẹ pari si rere

VRIGO Aug23-SEPT23)Ṣọra rẹ nitori owo mbọ wa yalowọ ṣ po rẹ ijogbon kan nfẹ bẹ silẹ.

LIBRA(Sept-24Oct22)gbogbo nkan ti o ba ṣe lojọ oni rere ni yiojasi ohuuayo yio ja si sakani sakani rẹ loni ki o maha je emimọ.

SCORPIO(Oct23-Nov22)Maṣe ṣeju ara rẹ lọ ẹlẹda rẹ ti mura tan lati ti ọ lẹhin nwọn o fun ọ ni ọgbọn ati oye Ọrọkọrọ ti nwọn ba fi lọ o gba yẹwo daradara ki o to fesi nitori ewu wa nibẹ,

SAGITTARIUS(Nov23-Dec21)Ọjọ oni gan ni ọjọ ti ọwọ rẹ yio ba ohun ti ofẹ toju ara rẹ daradara nitoripe ko nṣe eyiti a dara ni ọwọ re yio tẹ.

CAPRICORN(Dec22-Jan20)Ọrọ rẹ nfẹ ifọwọ sọwọ

# Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ. Etutu ṣiṣe Iwosan ati egbogi ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku koni yọọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja si rere awọn baba awon ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mọ Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ ṣaṣa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaiya pe arun tabi Amodi kan le pa ọ Ive owo 25/-

Turari Ẹyọ u Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ṣure rẹ Ajẹ ati abatenijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwọ ko ni mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba re idabobo siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| ati agbara Psalm ẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Ara | 30/- |
| Tailos Measurement works | 2/- 6d |
| Iwe kiri iyege Ikọṣẹ (Certificate of Apprenticeship) | 5/- |
| eyọ kan | 12/- 6d mẹta |
| Iwe Adehun larin Onile ati mehaya Tenants (Agrement Form) | 10/- 6d meji |
| Iwe Aṣofofo Aleo (Visitors not Book) | 2/-6d |
| Iwe Alagbafọ (Laundry Book) | 5/-6d |
| Kadi ifisọrọ sinu redio lọfẹ | 2d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan fun itaja ati Iṣẹgun Ajẹ | 16/- |

## APJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọsi ti onlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere bi, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilo Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ti ile itawe wa wa. Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rira adirẹsi mi niyi:—

**J. O. Shoyinka**

c/o Postal Agent.
1, Isiba Street
Itirẹ Via,

# UROLYSN DRAGES'

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ ti ẹnu. ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ a tabi tlọ-jijo eniaitọ ririn, rukuruku sẹ,ọn, aikoleri itọ lat ọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹ. Ejika wiwu tabi riro;



Ara sisan. titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaju loru nigbakugba, ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi, ba wọn yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti aiafia yio si de si ọ. Mej rẹko si ni ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi mi ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun o, maṣe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abo 6/od owo Ọkọ Sile kan abọ (1/6d)

Bere Egbogi yi ni ṣọbu awọn:-

NIGERIA MEDICINE STORES
4' TIUNBU SQUARE, LAGOS

# ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

## Ọṣe Lo Nsiwaju Ekun, Abamọ Ni Ngbẹhin Ọrọ

Lati Ọwọ Akọwe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ọkunrin kan wa ni ileto kan nigba atijọ o ni kẹtẹkẹtẹ kan ati aja daradara ni akoko kan, ibujẹ ẹran ni o fi kẹtẹkẹtẹ na si lati ma gbe. O si nko ọpọlọpọ onjẹ fun un lati ma jẹ nibẹ. Aja ti o ṣe ẹniki eji kẹtẹkẹtẹ yi jẹ alarekereke orisirisi ọgbọn ẹwẹ lo mbẹ lọwọ rẹ, on si ni oluwa wọn fẹran ju, ọkunrin na ki i lọ sọde ki o ma mu nkan wa fun Aja yi, ntoripe ti o ba ti de ni aja yi yo ma yọ, ti yio si ma fo mọ olowo rẹ ti bi yio fi un ẹnikẹni ti o ba ri wọn, Aja yi ki ṣiṣẹ, ere ni o ma nfi gbogbo ọjọ aiye rẹ ṣẹ.

Ṣugbọn kẹtẹkẹtẹ ro pe iṣẹ ti pa on lori pupọ ju, on ni yio lọ ko agbado, on ni yio si ru igi ati ẹru miran lati oko wa si ile. Nigbakugba ni inu kẹtẹkẹtẹ yi ma mbajẹ fun iru ipo wahala ti o ro wipe on wa, a si ma ba aja jowu nitori o ro pe gbogbo nkan ndan fun laiko sisẹ rara, ko gbagbọ pe aiye ki dun fun ẹnitiko ba ni iṣẹ lọwọ, o fi ara rẹ we aja, ẹniti oluwa wọn iwa ọlẹ baje.

Ki nma fa ọrọ lọ titi kẹtẹkẹtẹ yi ro ara rẹ pin, o si bẹrẹ si ro ọgbọn ti yio lo lati fi gba ara rẹ silẹ lọwọ wahala ti o nṣe Ni ọjọ kan, kẹtẹkẹtẹ yi ja okun ọrun rẹ lojiji, o si ṣe lakalaka wọ inu ile oluwarẹ o bẹrẹ si ti nipa kikan o nyọ mọ oluwarẹ, o si tun mba kiri inu ile, o si da gbogbo ile ru, ọ ba ọpọlọpọ nkan jẹ ninu ile, o kan gbiyanju lati mọ fo yile, oluwarẹ gẹgẹbi Aja ti nṣọ nibiti o ti nṣe eyi lo ti fọ awo tinganran, Tọbila ati iwọn nkan miran ti a fi kan ṣe.

Lẹhin eyi o tun fẹ ma Lehu ẹṣẹ oluvarẹ nibati awọn ọmọ ọdọ olowo kẹtẹkẹte yi gbọ iru ipo ti ogawọn wa gẹgẹbi kẹtẹkẹtẹ na ti ṣe da loni gbogbo ile ru were wọn ti sare wọle lati gba ọga wọn silẹ.

Nigbati wọn wọle wọn lu kẹtẹkẹtẹ na ni aludjubolẹ, wọn fi kumọ nla lu de ibi ti ẹmi fẹrẹ bọ lẹnu rẹ, pẹlu ironu nlanla ni kẹtẹkẹtẹ na fi pada lọ si bidujẹ rẹ ti o si tun bẹrẹ si da ara rẹ lẹbi pe. Emi ni mo ṣe ara emi ni mo fi iya nla yi jẹ ara mi.

Kini se ti nko ni itẹlọrun lati mi siṣẹ pẹlu awọn ẹlẹgbẹ mi, kini se ti mo fẹ lati ma ṣe ọlẹ biti aja keke-re alaini lari yi? O ṣe! o ma ṣe o o ri mi buru, bayi ni kẹtẹkẹtẹ yi tun kabamọ gbẹhin.

Ẹniti o ba fi oji sisẹ yio ni isimi nikẹhin, nitorina ẹ jẹki a ma ni itẹlọrun si ipo ti a ba wa o, oj koko ro ko dara o ẹnyin ọmọde o di ọwọ yin o, mo ro pe itan kẹta alainitẹlọrun si ipo rẹ yi yio jẹ ari kọgbọn fun yin o.

## Alọ o ? Alọ

Lati ọwo Abiọdun Omidiji ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

Ọwọ asọ jankulubọ ọwọ ẹwu jankulubọ ode fila jankubo– Ẹṣin sin.

Ajibẹlaọmọ ọshin ojojumọ lo rorin idẹ Atupa.

Oku oke odo antubọ on fẹ eyin tẹe -Agbado.

Agbogbo meji lọsi ode ako mọ ẹgbọn ako mọ abu ro - ẹsẹ.

Ani ki ojẹ ẹ an ọjẹ ẹran ani ki ojẹ egun gun oni ohun ko ni eyin – Ọbẹ.

Owo ẹwu irin ọwọ sokoto irin edefila irin -ekuro

Gbogbo ile yi ayika ayika odo.

Aboyun kọ sọ ọmọ inu rẹ ki pẹlẹ- Ago,

Panpa rikiti ẹpan lata ri - Ibẹpẹ

Mo su barakata mo fi ewe barakata bo- ọrun ati Ile

Ile kotopo kiki ekan- ẹnu

Alọo Alọọ Aji tuu maka ẹni -AjA,

Oji kutu omi wẹlu baro -koroba.

Asọ ẹsin mọ ile gọgọ rẹ ngọ ni ita- efin.

Adudu laro Afuu abẹ irin -ori.

Oju gbo ṣekete kiki ẹdun - Ina ori.

Abẹ ni ori kege oṣẹjẹ bara oni ohun aba wọn ṣe ọjọ oni koru- ọgẹdẹ-

Igi wo le gi ọpẹ wo le ọpẹ ti nu rẹ nsọ takuraja kege -obo ati oko.

Ọkọlarodo kọla pon ini sinu- Agbọn.

Gbogbo igi oko wọ ewe marawe ko wọ ewe O- Ọpẹ

## E Nlẹ Nbẹnun O!

Mo ki gbogbo ẹnyin Ọmọde, ẹ ku iṣe mo lero pe nisiyi gbogbo yin ni ọwọ yin yio di ni ile-Ekọ yin nitori mo mọ daju pe pupọ awọn ile-iwe ni nwọn ti bẹrẹ idanwo ni ana, awọn miran yio si tun bẹrẹ ni ọtunla, Oluwa ki o ran yin lọwọ o, E mura lati le ṣe dada ninu idanwo na, bi otilẹ jẹ pe idanwo yi ki iṣe eyiti nwọn o fi gbe yin si aye giga ṣugbọn idanwo yi ṣe pataki nitori eleyi yio tun ran yin lọwọ ninu idanwo ipari Ọdun.

Mo si ki ẹnyin ti ẹ wa ni iwẹ kẹfa pe ẹ ku ipalẹmọ idanwo ti Ijọba ti o ku oṣu meji loni imọran mi si yin ni pe ki ẹ mura lati isisiyi lọ lati ma ka iwe yin ni ile ohun ti oba ru yin loju ninu ohun ti ẹba kọ ni ile-i we ẹ fi han awọn ti o ba mọ iwe ju yin lọ lati la ye yin yekeyeke asiko wa fun yin nisisiyi lati ma ka iwe ẹma jẹki o di igbati idanwo na ba ku ọla ki ẹ to ma sare kiri. Oluwa yio ran yin lowọ.

Ẹnyin Ọmọ ile-iwe ejọwọ ti ẹ ba jade ni ile-iwe ti bi ẹ nlọ ni, ẹye ma bẹbẹ fun moto ọfẹ, Ẹnyin ti ile iwe yin ba jina, ẹma bere owo moto lọwọ awọn obi yin ẹ ye ma tọrọ moto wọ.

Gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ pe awọn gbọmọgbọmọ pọ lode oni, igbagbogbo in a mọ gbọ pe nwọn gbe ọm ọ lọ Ọmọ nwọn yio lọ si ile iwe, ti o ba to esiko ti o ye ki ode ile nwọn ko ni ri, nwọn yio wa titi nwọn ko ni ri.

Mo bẹ ẹnyin ọmọ ile iwe ti ẹ ba ti j de ni ile iwe ile yin n ki ẹ ma bọ ẹ ma ma tọro moto wọ mọ tabi kiẹ ma kigbe ẹ jọwọ ẹ gbe wa sa ẹfi owo ti awọn Obi yin ọ moto.

Ẹmura si ekọ yin o.

Odigba kanna o,

Emi ni tiyin,
A borọ dun Awọn Ọmọde

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kesan oṣu kejọ ọdun yi (9/8/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Atete de ṣe pataki

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba


# Akiyesi

Si Gbogbo Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ ni Abẹokuta ati agbegbe rẹ Ti o ba fẹ ra Irohin Imọlẹ ti o njade ni Ojojumọ lọ ra lọwọ Asoju wa Omidan Owokọya.

Owo Bookshop
Shapon go - Oko Road
ABẸOKUTA

Ti Enikẹni ni Irohin Imọlẹ, kọbọ meji pere.

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBO BO LAWA

No. 765, SATURDAY, AUGUST 8 1964 (2D)

## Obande Fẹ Ṣe Abẹwo Si Ilu Oyinbo

EKO:— Alakoso eto Ida iṣẹ silẹ fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Ọlọla Jacob C Ọbande ati Igba keji akọwe rẹ Mallam A, Tatari Ali yio ṣe abẹwo si Ilu Oyinbo fun eto ẹkọ kan lati lọ kọ ẹkọ lori eto ida iṣẹ silẹ ati lati lọ tun kọ ẹkọ gẹgẹbi nwọn ṣe fun awọn akẹkọ ni ẹkọ lori eto ida iṣẹ silẹ.

Ọgbẹni J, C Obande ati igba keji akowe rẹ yio lo ọjọ mejidinlogun ni ilu Oyinbo fun eto abẹwo ẹkọ na, Ọgbẹni Ọbande ati Igbakeji akọwe re yio fi ilu Eko silẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ti nwọn yio ba ọkọ Ofurufu lọ si Ilu Oyinbo.

Ninu awọn ilu ti Ọgbẹni Jacob Obande Igbakeji akọwe rẹ Mallam A. Tatari Ali yio ṣe abẹwo fun eto ẹkọ na ni Londọnu Stokhoma Sweden ati Edinburgh awọn ilu na ni nwọn yio sikọ ẹkọ lori awọn eto tojẹ mọ eto Ida iṣẹ silẹ ati nipa nkan miran.

Ọgbẹni Ọbande ati Mallam Tatari Ali yio fi ilu Oyinbo silẹ ni ọjọ eti ti se ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi pada silẹ Nijiria.

### Adegbenro Sọ Pe:

# EGBẸ DẸMỌ TI BA IPINLẸ IWỌ ORUN JẸ

ABẸOKUTA:- Adele o ori ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji Dauda Soroye Adegbenro sọ ninu ọrọ rẹ fun awọn oniwe Irohin ni ilẹ rẹ Adetayọ Lodge, Lafẹnwa. Abẹokuta nib ipade to ba awọn oniwe Irohin ṣe enipe yi pe ẹgbẹ Dẹmọ N N D P eyiti oloye S L Akintọla Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nṣe olori rẹ pe nṣe ni na wọn tun nba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria jẹ si ni bayi,

Alhaji D S Adegbenro tun sọ pe eto aje alatia ati ilọsiwaju ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tun ba jẹ pẹlu ati pe ẹgbẹ Dẹmọ nis siyi tun da ṣubu lu awọn ilẹ ẹkọ giga ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Alhaji Adegbenro tun fiye wa awọn oniwe Irohin pẹ Ijọba Akintọla ti gbero lati ma da awọn Olukọ ile ẹkọ giga duro lẹnu iṣẹ nitoripe awọn olukọ ati awọn ọga ile ẹkọ giga na kofara mọ ẹgbẹ Dẹmọ sugbọn nigbati oloye Akintọla ri pe Ọpọlọpọ awọn ile ẹkọ lojẹ ti awọn eni ṣẹ Ọlọrun o oye



Oloye S L, AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Akintọla tun gbero lati jẹ pe ki nwọn ma gba awọn olukọ na lemọ ilẹ ẹkọ ti nwon tiwa tẹlẹ tabi ti wọn koba gba bẹ ki wọn fun wọn ni owo oṣu mẹta ki nwọn si da awọn olukọ bẹ duro Alhaji Adengbero tun ṣọpe oloye Akintọla tun fẹki awọn enia mafi ami ẹgbẹ Dẹmọ si aya ki nwọn le mọ pe nwọn se ti wọn

Alhaji Adegbenro tun ṣe alaye fun awọn oniwe irope ki oloye Akintọla leri pe nwọn gba imọran ti ẹgbẹ on, Alhaji Adegbenro sọ pe nṣe ni awọn tun nyan awọn igbimọ Alakoso eto ẹkọ miran ti nwọn si nyọ awọn ti o ti wa nibẹ tẹlẹ kuro ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria,

Alhaji Adegbẹnro tun sọ ninu ọrọ rẹ pe eto ẹkọ ni ipinlẹ Iwọ Orun bayi si ti fẹ di ohun iparun patapata lori eto ti Oloye Akintọla nlọ bayi ati pe Alhaji Adegbenro si kesi Oloye Akintọla lati ro ori rẹ dada nipa eto ti ẹgbẹ rẹ fẹ mu silẹ bayi ati pe ki nwọn si ro ti awọn enia ipinlẹ na.



Alhaji D. S. Adegbenro
Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

### ISỌ ỌJA SHAPON

Alhaji Adegbero tun fi ye awọn oniwe irohin pe gbogbo isọ to wa ni ọja titun ti nwọn ṣẹṣẹ kọ si ilu Abẹokuta ni awọn igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta ti nsọ fun awọn enia ti nwọn ba jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ti nwọn ba gba ninu isọ ọja titun na pe ki nwọn fi ọja na silẹ patapata.

Alhaji Adegbenro tun sọ pe eleyi fi han gbangba pe lati fiya jẹ awọn enikenia ni awọn ẹgbẹ Dẹmọ si ṣe eleyi fun ati pe o yẹ ki a gbe oye le lati ri pe awọn enia to gba isọ ninu ọja titun na lo san owo asan tẹlẹ ọdun meji eyiti owo rẹ si jẹ pọnun mejidinladọta(£48)

Alhaji Adegbenro tun sọ ninu ọrọ rẹ pe awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Aalakukọyio gbe ọmọ na de ile ẹjọ ti awọn Igbimọ Afunsho ti Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta eyiti ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D P. nṣe akoso rẹ ko ba tete jawọ kuro lori ọrọ na.

Alhaji Adegbenro sọpe awọn igbimọ eto Ibo si ti ṣe eto lori ijoko ti yio wa kakiri ilẹ Naijiria Alhaji Adegbenro si sọ pe Ijọba to ti wo ati Ẹgbẹ tẹlẹ jẹ marun si mẹta bayi ni ile igbimọ aṣofin ti apapo ijọba ilẹ Naijiria,

Alhaji Adegbenro tun ṣe alaye pe ko yẹ ki ijoko ti yio wa ni Ẹgbẹ dinku rara atipe awọn ẹgbẹ Dẹmọ ti Ẹgbẹ tu wa ni ile Igbimọ asofin apapa Ijọba ilẹ Naijiria ko si sọrọ rara lori gẹgẹbi nwọn ṣe pin ijoka na.

Ni ipari ọrọ Alhaji Adegbenro, oni on kesi awọn ọmọ Ẹgba lokunrin ati lobinrin ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ lati le sọ ẹdun ọkan won fun awọn igbimọ eto ibo nigbati wọn ba pe si ipinlẹ Iwọ Orun ni ọjọ 'Bo ti iṣe ọjọ ketala oṣu yi lati ri pe ijoko mẹrin to wa ni Ẹgbẹ ko gbọdọ dinku si mẹta rara ni ilẹ igbimọ asofin ti apapọ ijọba ilẹ Naijiria,

Alhaji Adegbenro si sọ pe ohun to ye ki igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibile Abẹokuta ṣe ni yẹn ati pe nwọn ko si fi si ẹdun ọkan wọn rara

### Lati Oju Ewe Kini

Oloye Kosokọ so pe on kọ gbọ pe idile Eshilokun yio mu on sile gẹgẹbi ẹniti yio jẹ ọba ilu Ekọ. Oloye Kosọkọ tun sọ pe on ko ti gbọ lati ẹnu awọn idile Eshilokun on ni yio jẹ oye Ọba Ilu Eko.

Irohin tun fi yẹ wa pe awọn Oloye Ilu Eko si pe ipade kan si ogba ile adajọ agba fun apapọ ilẹ Naijiria Oloye Adẹtokunbọ Ademọla lati le lo pari Ija to wa larin awọn oloye marun na ati Oloye Ọba Adele.

Irohin na tun fi ye wa pe gbogbo awọn ọmọ Ọba lo ṣe ileri pe nwọn yio ṣe ipade kan ninu ipari ọsẹ